# Bibeli fun awon omode



# Olorun dan ife Abrahamu wo


Ikosile gba owo: Edward Hughes

Ayaworan: Byron Unger; Lazarus

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Olu'lo: M. Maillot; Tammy S.


Itan 5 ti 60


**www.M1914.org**

***Bible for Children,*** *PO Box 3, Winnipeg, MB R3C 2G1 Canada*



Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.


Èdè Yorùbá

Yoruba







Sugbon Abrahamu ti ko Lati gbekele Olorun nigbati koye. Li kutukutu owuro ojo keji, ogbera Lati losi ori oke irubo pelu Isaki ati eru meji.
3
Ki Abrahamu to jade, omu igi idana dani. Abrahamu pinu Lati gbo ti Olorun.
4
Li ojo keta won sumo ori oke na. Abrahamu so fun awon eru re wipe "eduro nihin,
awa yio lo lati sin Olorun, a o si pada wa si odo nyin".
5
Isaki bi Baba re, "aguntan irubo da, Baba a mi?" Abrahamu daa lohun: "Olorun yio pese aguntan fun ara re".
6
Awon mejeji wa sibiti Olorun ti yan, Abrahamu te pepe, osi to awon igi irubo si Olorun. Abrahamu ti te opolopo pepe tele ri sugbon, pepe yi je ohun to nira fun.
7
Abrahamu mu Isaki. Ode lowo-lese, osi te omo re tofe si ori pepe. Se Abrahamu yio gboran si Olorun lati fi omo re kan soso rubo bi?
8


Beeni! Obe na sana nigbati Abrahamu gbe soke. Iberu lemaa mu li okan sugbon Abrahamu mo wipe ohun ni lati se gboran si Olorun.
9
Logan, Angeli Oluwa ke li ohun rara, “Dawoduro! Nisisiyi, mo mo wipe o beru Olorun. Iwo ko da omo o re kan soso si kuro lodo mi”.
10
Ni kete, ori eran agbo ninu igbe to wa ni itosi, Abrahamu tu Isaki sile, osi fi eran agbo rubo dipo o re.
11
“Olorun ti pese gegebi Baba mi tiwi”, Isaki ro eyi ninu ara re.
12
Nigbati Baba ati omo re nsin Olorun, Angeli wi fun Abrahamu wipe, “Ninu awon omo re, gbogbo orile-ede ni yoo di alabukun fun nitori wipe o gboran.” Li ojo kan, a o bi Jesu nipase okan ninu awon iran Abrahamu.
13
Abrahamu ati Isaki pada si Ile. Lehin saa kekere, Sara aya Abrahamu se alaisi. Abrahamu ti se oloogbe aya re, Isaki pelu ti se oloogbe Mama re.
14

Lehin isinku, Abrahamu ran erukunrin re agba lati wa aya fun Isaki. Erukunrin na lo si ilu Abrahamu lati lo wa aya laarin awon ebi Abrahamu.



15

Erukunrin na bere ami kan lowo Olorun. "Jeki iransebinrin ti oba bu omi fun awon ibakasie wonyi je eniti o yan li Aya fun Isaki".



16

Logan, Rebeka bu omi fun awon Ibakasie. Oje okan ninu awon ebi Abrahamu. Erukunrin na si mo daju wipe Olorun ti gbo adura a re.



17

Rebeka fi awon ebi re sile lati fe Isaki gegebi oko re. Rebeka tu Isaki ninu Lehin iku Mama a re. Isaki feran re lopolopo.



18

Olorun dan ife Abrahamu wo

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Genesisi ori mejilelogun titi de merinlelogun

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese.

Olorun feran wa tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Nisiyi Olorun le dari ese jiwa.

Bi o ba fe yi pada kuro ninu ese re, so fun Olorun bayi wipe: Olorun mi owon, Mo gbagbo wipe Jesu ku fun mi osi ye. Jowo wa sinu aye mi ki o si dari ese mi jimi, ki emi bale ni aye otun nisisiyi, kiisi ba o gbe titi lailai. Ranmilowo lati gbe igbe aye mi fun o gegebi omo re. Amin. Johannu ori keta ese kerindinlogun.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!